# EKO AKETE.

## IWE IROHIN O'ṢỌṢẸ.

ỌRỌ IFỌJUSUN:—
"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi".—W. T. Stead.

Vol. I. No. 44. SATURDAY, MAY 12, 1923. Fourpence.

*Editor & Proprietor:*—
ADEOYE DENIGA,
*Office:* 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

**N. V. HANDELMATTSCHAPPIJ V. H.**

J. F. SICK ati AWỌN ẸGBẸ.

No. 7, Ita Ibode laiki, l' eti *Glover Memorial Hall* (*Customs Street,*) EKO





Awọn Oyinbo Onişowo yi nranşẹ Masini-aranso ti a npe ni VESTA Nos. 1-4 t' ọlọwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju a le fi iye-owo wọn han ẹnikẹni to ba lọ si Ile-owo yi.

Nwọn mura tan lati şe adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ranşẹ Mejila tabi jubẹ lọ ninu Masini na.

Awọn Oyinbo yi nşe orişirisi Ilẹkẹ alarabara, nwọn si nranşẹ *Cement* ati panu kikọle to nipọn, ati ẹja Abọmafọ ati orişirişi ọja

Ilẹkun Ile awọn Oyinbo yi şi nigbakugba ti enia ba fẹ lati lọ ba wọn sọrọ Asiri nipa Owo. Irohin ko to afojuba.

STEVEDORING COMPANY.

.LL STEVEDORING WORK

at lowest possible prices anywhere in the Lagos area.

ODS HANDLED CAREFULLY AND EXPEDITIOUSLY.

es given for the handling of goods under any circumstances

*PRICES ON APPLICATION*

TO

**S. I. M. Johnson,**
9, Scale Square,
Phone 227 Lagos,
P.O. Box 498.

ỌGBẸNI J. C. VAUGHAN.

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun kikọle fun tita ni owo ọpọ-u-ọyọku.

O ti ṣowo Irin Iṣẹ lorisirisi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awọn oniṣowo Irin Iṣẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ ọ.

ỌGBẸNI DURO THOMAS.

ONIṢOWO PATAKI.

Ti 55, ita Faji, l'Eko, ni orisirisi Ọja to de fun u lati Ilu Germany fun tita: awọn nkan Awo abọmafọ, Cement, Akara, ati ọpọlọpọ ọja miran.

Ẹ lo de ibẹ, Igbo-Akan 'mọpa ni ohun to ni

Bi ẹ ba fẹ, ẹ kọwe si i, *Number* Apoti-Iwe rẹ ni Ile ipin iwe (*General Post Office*) ni *374*. *Number* fifi-ẹrọ manamana ba a sọrọ (*Telephone*) ni 243.

Ẹ WA RA ỌPỌ ỌJA.

Ọgbẹni D. B. OṢUNTOLU, onisowo Ọlanrewaju ni ọpọlọpọ ọja fun tita ni Ṣabu rẹ ni No. 44 Balogun Street, l'Eko.

Ninu awọn ọja rẹ ni iwọnyi:—Ikoko taba, Carpets Panu ikọle, Aṣọ oniruru, Itẹko, Baranjẹ, Olowonyọ, Yọmini, (*Satten*.)

Ati orisirisi nkan atata miran, Ọja Ọgbẹni yi rọju o si lere ninu, ọpọku-ọyọku ni.

Ẹ lọ ra ti nyin nibẹ.

WHAT IS MORE REFRESHING than a sound sleep on a comfortable Bed? or time-saving than a thoroughly good sewing-machine?

A large consignment of Brass Iron-Beds, Bedsteads, (new arrivals from Germany.) hand and Treadle-sewing machines "Gritzner" is just to hand at Mr. Duro. Thomas's establishment 55, Massey St., Lagos.

An early call at this address for your selections will well reward your labour.

Prices attractive and alluring.

CALL TO-DAY NOT TOMORROW.

KILO NGBE MI LỌ YI O? ORUN!

AṢỌ NYIN FAYA, Ẹ LỌRAN.

AṢỌ NYIN FAYA, Ẹ LỌRAN.

IBUSUN-ILESANMI ati

MASINI-A-NJUWON

Ọgbẹni DURO THOMAS.

Onisowo-towolawi, ni awọn IBUSUN mèrémèré onidẹ to sẹsẹ de fun u pẹlu awọn MAṢINI iranṣọ ti a npe ni *Gritzner* ọlọwọ ati ti ẹlẹsẹ, lati ilu Jamani wa fun tita ni Ile Ọja rẹ 55, Ita Măse leti ita Faji, l'Eko

Ifa mbẹ fun awọn to ba tete lọ ra tiwọn nibẹ: owo yẹpẹrẹ ni a nta wọn, bẹni awọn Ọja na si "ka 'yin" to.

E lọ ba Àwúre nyin pade nibẹ.

## GBOHUN-GBOHUN.

O RI AGBEBỌ ADIẸ LỌJA O SARE SI I.

Ninu awọn ọrẹ wa ti nwọn ṣakiyesi Ẹja inu panu ti awọn ọmọde okiri ni'lu nisinsinyi yio ri pe igbamiran nwọn a ma ta emi ni bi *Sardines* ti o to Ṣile kan tabi Nain (9d) fun ẹyọ kọkan, ni Tọrọ tọrọ tabi Kọbọ meji meji, aṣe bibajẹ ni gbogbo awọn ẹja tabi awọn ẹran inu panu na bajẹ lo jẹ ki wọn ma ta ni pọ ọ bẹ; ọpẹlọpẹ Ọgbẹni wa Dr. OGUNTOLA SAPARA to woye nkan yi, to si kọwe si awọn Alaṣẹ Ilera Ilu lọsẹ to kọja, pe ki wọn ma wọ Ṣabu ki ṣabu ti irufẹ ọja bẹ wa ki wọn si fi aṣẹ Ọba ko wọn; waraṣeṣa awọn Ọja bibajẹ yi ti di kiko danu bi iṣẹju. Bikoṣepe Ọgbẹni wa yi tete woyẹ ọran yi ni, ẹnu ki ba ti le sọ arun ti jijẹ awọn ẹja ati ẹran wọnyi le mu wa sarin wa ni bi. Olore ka ku, Ore! Olore ka run, Ore!! Towo Tọmọ ija wa!! ija wa!!!

Ẹ KU, DANSAKI, O YẸ YIN O!

Kolẹgbẹ ni ere (*Women at Work*) ti awọn Ẹgbẹ Oṣiṣẹ Iya afin ti *Church* Ebute Ero ṣe ni alẹ *Friday* to kọja ni Ile Iranti Afari Ogun l' Ẹhingbẹti, eyiti o wu ni julọ ninu awọn ere na ni ere Agbebọn ti diẹ ninu awọn Iya afin na ṣe, ninu eyiti CAPT. EUNICE O. WILLIAMS D.S.O. bi Ọgagun (*Officer Commander*) "ṣe bi arira" nigbati o npe iṣẹ fun awọn "Ṣoja" na ti o si "bẹri" fun Ọga rẹ *The Countess of Lagos* (Miss K. Macauley) Ibadi-aran; ẹlomiran ninu awọn oworan ko mọ igbati on ja'tọ fun iyara ti gbogbo awọn Ọmọge ṣoja na fi han, to si wú ẹnikẹni lori tobẹ ti awọn oworan tun fi pe wọn pada wa tun ere na ṣe lẹkeji lẹsẹkẹsẹ.

MISS GRACE COLE to ṣe oniwasu "fọgi" nigbati o fi wọ aṣọ oye rẹ B.A. Gbogbo ọrọ ti o sọ ni a gbọ ketekete o si dan maran tobẹ ti o si ẹnikẹni lori; MISS ABIGAIL AMOS to ṣe Olukọ Ọmọde ṣe daradara pẹlu, bẹ si ni Mr. WILLIAMS to ṣe *Lawyer* ṣe ka-si-nk lalẹ ọjọ na.

MRS E. ṢOYỌDE to ṣe alagbatọ (M "da bira" lọpọlọpọ o si ṣe ere r ẹnikẹni lori; bẹ gẹgẹ si ni Mrs. M. M. bi Igbakeji ọga, ṣe ibi ti a yan fun nit na daradara. MRS. SELINA ALAKA G to ṣe ọga won ko kẹrẹ, nṣe ni jagun tẹki nigbati o fi nwo gbogbo awọn onisẹ na.

A ba MRS. ALICE IṢOLA Se na yọ fun yiyọri ere na si rere ỌGBENI OLUWOLE ṢOYODE y dari ere na ti gbogbo nkan

IWAJU L'ERO

*Editor Eko Akete* npẹlẹ (*Lecture on Noted West Af series*): Ẹkeji ni ede wa, ni Onidunkun Oyinbo (*St. Paul School Room*) ni *Wednesday* (oṣupa yio ma ja tõ) ni alẹ. A o ṣe Asọye na pẹlu ẹni nlawọnyi.

*Bishop* Samuel Ajayi

Dr. Obadiah Johnson

J. A. Otonba Payne,

Ijoye Taiwo Olowo.

Ọgbẹni Dada Adeṣ gb Ọgbẹni Latunde Johnson, Aṣe-lẹbẹ-koro-janjan, ni yio yi. A o fi Iwe bembe w ri ra lọwọ Ọgbẹni *Editor* rẹ 24 *Williams Street* l' E ọna ni alẹ ọjọ na.

Ti awọn Ọmọde tọrọ-

Ti awọn Agbalagba

A o ta Iwe orin ni Ọgbẹni na ṣe ti ni alẹ ọjọ Ipade n le ri ra lọdọ *Editor*

Bata-koto yio afọ lẹhin ọgba.

### ỌWO A RAN IYOKU O.

ọn Ijọ *Bethel* ti Ilẹ yi ṣe etutu si Irin Aropodogiri mejila, ti nwọn nṣe si Ile Isin wọn titun ti nwọn ni Opoponla, ni ọjọrọ *Saturday* to gbogbo Ijọ ọmọ Ibilẹ *Africa* nibi lọ ṣe ẹyẹ na. Ilu ndun kikan si gbigbe ti a kọ ni ohun Ilẹ wa, ninu Isin Owo ti a ri kojọ ninu Ipade yi jẹ

### Y MA KAN NILE AKIMỌSA OJARE, ẸNIKEJI.

Ti Ile
*Excels*
ikọde ti Morounfolu Abayọmi *Lawyer*
O ti ...inya, yio fi oruka bọ Omidan
...hin Ini di *Hon.* & Mrs. Kitoyi Ajasa
AT...RI A*ch* Onidunkun Cyinbo ni
won onişowo *Thursday* ọsẹ to mbọ, owo
OKO

### Q...ATE, KO JỌ GATE O F'ẸSẸ MEJEJI TIRO.

Ti 5 Villoughby kekere, Olori Ọlọpa,
e fun ... i Duro Delphonso ti ita
kan Awo ... ni *Monday* ọsẹ yi fun ẹsun
pọlọpọ ọja ... nabọ ile rẹ niwọn oşu diẹ
Ẹ lo de i... ọna bayi o fẹ fi eru gbowo
o ni ... awọn Ẹgbẹ ti o nsan ofo
Bi ẹ ba fẹ ...*urance.*) A gbọ pe nwọn
ẹ ni Ile ...
i *374.* N...
ọrọ (*Teleph*...

### ...DELẸ OJU YAN ỌDẸ.

...gbẹni D. ...a nṣe akiyesi yio ri pe ọrọ wa nipa
ni ...ẹlẹ ninu ilu yi jẹ otitọ atipe bi ao

...nu awọn ... a ti kọ iwe nipa ti awọn oloye
...bero a ti fi role sinu Iga, a gbọ
Panu iko...abete. "Ṣalaporẹ inumẹ ndabete,"
Oloeke ti nwọn nfẹ jẹ oye lẹhin
... or şirişi nkan, pe awọn ni aşiwaju pupọ.
...lẹ jẹ oye pataki, atipe igba
o si lere ... Ẹ jẹ ka da lẹ ka tun ṣa.
Ẹ lo
P... ...ko ti rogbodiyan ti iwe omi
...ti Ijọba nwa awọn ọmọ
...n ko yọju lafaşe Ajayi
...a pe ọmọ Onilẹgbalẹ
ti gbogbo wọn wa
...e oye yi ko tọ si

Foyinbo yi, papa ninu awọn ti wọn nṣe kita-dayin wọnyi nwọn o ti ju ẹniti iba ma ga agborun (*umbrella*) le Oloye lori. Awọn wọnyi ni wọn ba ma jijadu oye ninu Iga Onilẹgbalẹ.

Laditan, Afisi, Atitẹbi, Jinadu Bonbata, Fatade Tokosi, Asani Akilagun, Liadi Ajenifuja ati ikan to wa ni Ijẹdẹ. Lẹhin awọn ti a ti ka wọnyi ni ọmọde kekeke kan wa nṣe kita dayin pe on fẹ jẹ oye, papa nisisinyi oye yi jina si ibi ọrun ti jina silẹ.

A ni ireti pe bi agbalagba ti a ti ka wọnyi ba mu ogiri si nkan Iga wọn nipa bayi ọmọde kan iba ti ri aye ati jẹ gaba lori wọn. Nitorina a bẹ awọn agbalagba ti wọn wa ninu Iga yi ki wọn ṣe iranti ati mẹlọ-mẹlọ ninu ọrọ oye yi, ki eyi ma ba ri bi ti Lagbaja. "Abamọ aşe aşetan o di apọn." A si gbọ pe ikan ninu awọn

ọmọde yi nsọ isokusọ si wa lara pe Foyinbo fun wa ni owo ni, yio dun mọ ni pupọ bi oluwarẹ na ba le fi ọwọ sọ aya ki o si sọ eyi sinu iwe irohin pẹlu orukọ rẹ ati iye owo ti o ro pe wọn fun wa. Afẹ ko da wọn loju pe Akirimanu ki işe alagaba-gebe enia, a gbọ ti eku wi fun ẹiyẹ nipa bayi a fẹ ki ọmọde yi lọ so agbejẹ mọ ararẹ nidi ki o ye la ala kurumọ (*Kroo boy*) lojojumọ awọn agbalagba ama pa ni owe pe Ika ti o ba wọ imu ni ankibọ Ajayi Foyinbo ti a nsọ ọrọ rẹ yi jẹ ọlọgbọn enia o si ja fafa gbajumọ rẹ si de gere.

Nisinsinyi a o dẹ oju silẹ lati fi woran ohun ti awọn agbalagba nfẹ şe, atipe atun fẹ tẹ mọ wọn leti pe "agbalagba ki wa lọja ki ori ọmọ titun ko wọ," ki owe na jẹ tiyin o.

AKIRIMANU

### ILE ẸJỌ GANRAN

Ile Ẹjọ ganran ti awọn enia Ọdaran tabi Alufin bẹrẹ ni Ọsẹ yi, Adajọ Agba lo şe Alaga ati Agbẹjọro Ọba Ọgbẹni C. W. Carey, gbogbo ẹjọ na jẹ mẹjọ ninu rẹ Oyinbo kan ti ile işẹ *John D. Fairly...* *& Co.* ti orukọ rẹ njẹ *Robert Smith Gordon* o wa ninu awọn Alufin.

A o fi irohin kikun rẹ sinu iwe Ọsẹ to nbọ.

Ẹjọ ganran ti Ilu Abẹokuta yio bẹrẹ ni Oşu yi, ijọ Tuesday ijọ kejilelogun, Ọgbẹni Ọlọla Onidajọ Agba *R. M. Combe* ni yo şe Alaga.

KỌLAWỌLE.

## Open Letters.

To Celebrities, Notorities, etc., in Different Walks of Life.

No. 3.

To
AINA ONABOLU Esq.,
*Artist.*
Onabolu Studio;
Campbell Street,
Lagos.

Worthy Artist,

I heartily congratulate you on your success in winning the £5 5s. od., Prize offered by The Nigerian Government for producing the best Poster for The Nigerian Section of the impending British Empire Exhibition as announced in *Reuter's Telegrams* of the 7th instant.

Little did some think, that when about a score of years ago, it dawned on you to cultivate your artistic talent with which, it goes without saying, you are naturally endowed, whilst pursuing "the even tenor of your way" in the local Marine Department with which you were then connected as a humble signaller, Fame awaits you in the Art in which you hardly spare yourself, in order to acquire thoroughness and efficiency; and the measure of success which is attending your efforts now, as never before, either as Lecturer in Drawing, in many Secondary Schools in the Colony, or as an *Interpreter of The Pencil and Brush* in sketching personalities from life, ought to be an incentive to others, whose talent in this direction still lies dormant, and only requires the magic touch of your artistic genius.

By this your recent public achievement in the competition (the first in the Annals of the Colony) in which, I understand, some Europeans, noted for their painting inclination, have taken part, you have proved once more to friends and foes, not having the good fortune to partake of our colour, that given the same opportunity, the African is NOT inferior to any other races in the cultivation of Science, Art, and Philosophy. May we have in you, *The Michael Angelo* of The African Race.

Again I congratulate you.

Eko Akete.

## ELETI ỌFẸ KO MỌNA O NDA PADE-PADE.

Ninu Iwe-irohin wa ti ọjọ 28 oṣu April to kọja a tọka *Article 34* ti *Articles of Religion* ti *Church of England* fun Oniwe-irohin "Eleti Ọfẹ" Nipasẹ *Article* 34, *Church of England* yọda fun *Church* ti ko ba si labẹ aṣẹ wọn ki nwọn ma da aṣa won ṣe, niwọn igbati irufẹ aṣa bẹ ko ba lodi si Ọrọ Ọlọrun, ṣugbọn Oniwe-irohin Eleti Ọfẹ yi fi aimọkan tabi eti 'kunkun rẹ han nigbati o sọ pe ọrọ ko ri bẹ; Ẹ gbọ bi o ti wi ninu iwe rẹ ti ọsẹ to koja :—"O tọka wa si *Article 34* ti *Church of England*, bẹni, a ri i; ṣugbọn oju gba wa ti fun ọ pe ko si nkankan ti o jẹ mọ ohun ti a njiyan rẹ ninu wọn. Ilana Isin yi ko kan Ijọ awọn enia dudu (*African Churches*) bikoṣe ti awọn Ijọ ti o wa labẹ Ijọ ti *Church of England.* Bi o ti se da luru mọ ṣapa nu."

Ẹnyin ọrẹ wa, ẹ ma ṣai ba wa ka *Article 34* na ninu Iwe Adura Yoruba ti C.M.S., *Page 517*, ẹ o ri igede ti nwọn fọ nibẹ pe *Church* ki *Church* ti ko ba si labẹ aṣẹ wọn le da aṣa wọn ṣe niwọn igbati irufẹ aṣa bẹ ko ba lodi si Ọrọ Ọlọrun.

Ọrọ inu Iwe Adura na ni eyi :—"Ko kuku agbara pe ki Itan ati Ilana isin ki o ri bakanna ni ibi gbogbo ki o si ṣe dede ; nitoripe nigba gbogbo nwọn a ti ma yatọ, a si ma pa wọn da gẹgẹ bi iyatọ ilu, ati igba, ati ilo iwa enia ; niwọn bẹ ti a ko fi ṣe ilana ohun ti o lodi si Ọrọ Ọlọrun.

Olukuluku tabi ororilẹ Ijọ, o ni aṣẹ lati da, lati parọ, ati lati ṣe ipare elo isin isin, ironu ti Ijọ Ọlọrun ti a lana silẹ nipa aṣẹ enia, to niwọn bẹ ki a ṣe ohun gbogbo si idagbasoke."

Ẹwẹ, ẹ tun gbọ bi Alufa Ologbe, Oyinbo H... Venn, B.D., ọkan ninu awọn Oyinbo to da I... C.M.S. silẹ nilu Oyinbo ni ọdun 1799, ti o *Secretary* Ẹgbẹ na fun ọdun pupọ, ti wi ninu Iwe kan ti a npe ni *Memoir of Henry Venn, Page* nipa ọran yi.

**"But our own Prayer-book has laid dow... principle that every national Church is at liber... to change its ceremonies and adapt itself to national taste."**

"Ṣugbon a ti fi eyi han gbangba ninu Iwe adur... wa pe *Church* ki *Church* ti o ba jẹ ti Ibilẹ le... aṣa tabi iṣesi wọn ninu Isin pada, ki irufẹ *Chur*... bẹ si ṣe ohun to baba iṣẹdalẹ wọn mu."

Ẹnyin ara, ẹ ko wa ri i kedere pe Eleti-O... *ku bi o li yan a?* nigbati ko mọ itan tabi kẹtẹk... ohun to ti nba ara rẹ ninu jẹ si lati iwọn ọjọ... wa ?

Ilẹkun ọrọ yi ti gbọnin-gbọnin sibi lati oni lọ.

Ed.—"Eko Akete."

Si Oniwe-Irohin
"Eko-Akete"
Lagos-Eko.

Ilarẹ Press
Ibadan
4/5/2...

Alagba,

Emi yio ṣe ọpẹ gidigidi bi ẹ ba le fun mi ... afo lati sọrọ tabi da si ọrọ "Iyan" to wa lari... ẹnyin ati Eleti-Ọfẹ nipa *Bishop* Oke : Ẹ jọwọ... ma ṣai jẹ ki a tubọ fun Eleti-Ọfẹ lesi nitori lọka... mi o dabi ẹnipe nwọn ran wa ni : o si yẹ ko g... esi ; ti o ba ṣe pe ọmọ Yoruba ni Eleti-(... o yẹ ko ma ronu jinlẹ, ko si ka ijinlẹ iwe pẹlu... ki o to ma sọrọ jade, lati ọjọ ti nwọn ti njẹ O... *Bishop* ninu Ijọ to wa (oko-ẹru,) lẹhin Olog... *Bishop* Crowther Enia dudu melo ni nwọn fi ... *Bishop* alaṣẹ ? O jọun pe ko si ni ilu nigbati nwọn... fi *Bishop* O———silẹ ti wọn fi *Bishop* J–... jẹ alaṣẹ, (ọrọ ti Eleti-Ọfẹ sọ lo mu mi ya... agba o, mo tọrọ gafara,) mo rope o y... tọka fun Eleti Ọfẹ bi ko bai ti ka iwe de bẹ Iwe mimọ eyiti o sọ ba yi pe :— Jer : 13 "21.

'Ara Etiopia le yi awọ rẹ pa da, tabi ẹkun le "yi a rẹ pada." Kini Eleti-Ọfẹ nṣe loko to di oru? A nki..., a nsa oni o mọ ẹniti oku" Awọn to ...n wa nbere igbawo ni ao ma adun ọrọ na ...e orin awọn Wesley—Nigbawo ni ọmọ ...rika yio ma adun ọrọ na." Ki ba ti ṣe Eleti-Ọfẹ to pe ara rẹ ni Oniwe-Irohin Yoruba to si nwa ire ilu re io nsọ iru ede pe *Superintendent* ki ṣe ipo *Bishop*. Ọmọ atiro ti o ba lọ ti ẹsẹ bo bata oro lo ma fẹ gbo o. Ki Eleti-Ọfẹ ko mọ pe ipo *Bishop* ni Ipo Ẹni-ọwọ Oke ati aṣiwaju rẹ ni haun, ki isi ṣe *Bishop* adawo ra————ki iyoku ma e o. Mo dupẹ afo ti o fun mi.

Emi ni tirẹ nitotọ

LAṢORE

*B'Ọlọrun ko pani.*

## EKO AKETE:

Eko, Saturday, May 12, 1923.

### ONIYEGE MA NI 'YAWO O!!!

Sàṣà ni ọkọ-iyawo ti irufẹ igbe oru-anjọ bayi ko dun mọ lẹhin igbati iyawo ...ba ti jẹwọ *wundia* fun u: nigba lailai, ...a si ohun abuku to rekọja-ala ti ọmọge ...ba gbe niyawo ba kuna ẹyẹ, ọla ati ...o yi: eyiyi si mu ki iwa-yiyege yi jẹ ...un ti o gbọrẹ-gijẹ larin awọn enia wa ...igbani: gidipa, Dr. Obadiah Johnson ...logbe sọ fun ni ninu Iwe Itan awọn ...oruba rẹ, (*History of the Yorubas*) ...we 115, pe "Didè ni awọn Yoruba ...na nde iyawo to ba ti ba ara rẹ jẹ lọna ...yi, nwọn a si na a, titi yio fi jẹwọ ẹniti ...ba a jẹ: a ki si ṣe e lọṣọ rara, iṣẹ ti ko ...ẹ ẹ ni nwọn a si ma ran a ti ko si gbọdọ ...ori rẹ bi iyawo: tulasi si ni fun u lati ...ọn omi sile."

Ṣugbọn ni ode isisiyi nkọ? Gbogbo ... yi kọ lo fẹrẹ parẹ tan baun? Ko ha di ...e ti awọn ọmọdan wa miran ba wa lọna, ...di ki nwọn ma nọga si ohun ti boya ipa ...ọn tabi ti obi wọn koi ti ka? Ibọsẹ-...omini (*Silk Stockings*) nkọ? Bata-oni-...ṣẹ (*High heels*) nkọ? Tabi ilẹkẹ-...un Iworo (*gold beads*)? Ẹ gbagbe 'Efi-niwa" ati oriṣiriṣi ohun ọṣọ ...an? Gbogbo irufẹ iwa ti awọn ọmọge ...i nhu bayi ṣiwaju gbigbe-wọn niyawo ko ha di mimọ fun awọn alagba onilakaye bi? Nigbati nwọn ba si de ile ọkọ tan, boya ti idaduro ba ṣeṣi wa fun liloyun wọn, nwọn a sọ-ẹjọ di ẹjọ oloko-ẹṣin: ti o ba si jẹ pe a ri diẹ ti a fi ẹbun Oluwa (eyini ni ọmọ) yi ta lọrẹ, ko ha ni di ijaya ọkọ ati awọn ẹbi toku pe ki ẹniti o ṣẹṣẹ bimọ na maṣe ba a rin: ilu wo ni a ti i gbọ iku awọn ọdọ-obinrin pāpā lẹhin ọmọ-bibi wọn to Eko? Ko ha di pe ko di ẹru-jẹjẹ fun ọkọ ti obinrin rẹ ba loyun pe on ko mọ bi ori on yio buru bi ko ni buru lẹhin igbati obinrin na ba bimọ tan. Ti a ba bẹ idi nkan wọnyi wo, a o ri pe lilo ti awọn *wundia* miran nlo ara wọn ni ilo-kulo (ki o ma a ro kĩ ninu nyin!) ṣiwaju igbeyawo wọn, jijẹ egbogi lọna odi, ai-jẹun ti yio fun wọn l'okun, gigelẹtẹ nigbati nwọn ba wa loyun, tabi nkan miran ni a ro pe o nmu eyi wa.

Boya a le ri awọn obirin ti yio p'owe mọ awa ọkunrin pe "Ajala tani na ọ, ṣe ẹnyin na ni"!! Otọ leyi, ṣugbọn, awa na tun le fesi pe "A ngbeja ọja, ọja ni tani nja lẹhinkule on?" Eyi ko wipe ki a ma tọka ewu ti a nri nigbagbogbo ni igboro yi larin awọn ọmọdan miran ti a ba ṣẹṣẹ gbe niyawo bayi.

A dupẹ pe gbogbo awọn ọmọge wa kọ lo ni irufẹ iwa bayi lọwọ: a ri ọgọrọ ti nwọn njẹwọ ọmọluwabi, papa ki a to gbe wọn niyawo. Adura wa ni pe ki irufẹ awọn bẹ ma ṣai ma pọ si i, ati pe ki ṣiṣẹku awọn ọdọ-aya, pẹlupẹlu lẹhin ọmọ-bibi ma ṣai dinku larin wa.

Ki Ọlọrun ma fi Ọlọjọ ranti!!!.

WANTED.

A good Cook capable of preparing all kinds of Native "Chops."

Good wages to a suitable man.

Apply to the Editor of this Paper.

# SINGER ! SINGER !! SINGER !!!



Kinla!! Tiwa ki nșe a nșeșe wa onibara, kini a ti nș'oku l'ọrun, nwọn pọ to wọbi larin orișirișị enia jakejado Nigeria.

Ẹrọ iranșọ " SINGER " kọkan, ni gasikia polowo ara rẹ.

Pataki ohun ti o mu ' Ẹlẹha jade ọsan ' ni wipe a nfẹ mu wa si akiyesi awọn ogunlọgọ onibara wa

## TI ẸDINWO NLANLA TI A ȘE

ninu owo ẸRỌ IRANȘỌ wa ati IRIN-IȘẸ wọn, eyiti o fẹrẹ ba iye owo ti a nta wọn ki ogun Jamani to bẹrẹ nijelo mu.

---

wọnyi ni diẹ ninu awọn ohun pataki ti o jẹ ki ẸRỌ IRANȘỌ SINGER t'idi awọn ẹrọ iranșọ miran b'omigbona.

Ikinni.—Ẹwa, itẹju ati idakẹ rọrọ l'ẹnu ișẹ.

Ikeji.—Irọrun ti o wa lati ri orișirișị irin ișẹ rẹ ti o ba bajẹ ra.

Ikẹta.—Ifọwọsọ'ya lati tun gbogbo Ẹrọ Iranșọ 'SINGER' șe nigbakugba l'ọfẹ ibașepe a ra lọdọ w tabi ni Ẹka-ile ọja wa miran.

Wa bere iye owo wọn ni Ile-ọja wa ni Popo nla l'eko nibiti ' Ẹrọ Oyibiri ' nl'agogo.

Phone L222, Extensions 2 & 3.
P.O. Box 171.

DADA ADESHIGBIN & SONS,
*Sole Importers Singer Sewing Machines.*

---

ỌGBẸN' OYINBO ONIȘOWO

**R. S. JAMESON**

Ti Opopo-Nla

Ni Iyọ to funfun bi Lekeleke fun tita ninu Apo ogoji Iwọn, £5 10 o lo nta a fun *ton* kọkan
Ọrẹ, lọ sibẹ, mașe jẹ ọbẹ obu o !

**To whom it may Concern.**

The Public is hereby notified that Mr. B. O. JOSEPH of 64, Breadfruit Street, who had wanted to Raffle his Motor Car has decided not to do so again and has instructed his Driver who carries the list about to refund money to those who have paid

Lagos, 13th April, 1923.

To the Editor "EKO AKETE."

Ọgbẹni,

Jọwọ gba mi ni aye diẹ lati la ọrọ gbolohun meji tabi mẹta fun oniwe-Irohin Eleti-Ọfẹ nipa iriyanjiyan eyiti omu oniwe-rohin yi lati ma sọ Aɔrọ odi si aṣiwaju rẹ, nitori ọrọ *Bishop* ko ṣe *Bishop*.

Ninu iwe irohin to ba ọkọ *Appam* wa, lati Ilu Aganyin (*The Gold Coast Leader*) a ri ka wipe Pope ti Romu fun *Lawyer* J. E. Bucknor, ti ilu aganyin ni oye *Knight of St Gregory the Great* nipa iṣẹ re si Ile Ọlorun ti Ijọ Aguda ni Ilu Aganyin. Njẹ ale bere wipe bo ba tọ fun ọgbẹni yi lati lo tabi ko tọ nitori pe, oye yi ko ti ọdọ ijọba Gẹsi wa, oye ti Ijọba Gẹsi ni *Knight* ti *St. Michael* ati *St. George*, oye ti ọgbẹni yi ni ti *St. Gregory* eyi fi han ni pe, onikaluku le jẹ oye ba fẹ ni ọna tirẹ.

Ẹwẹ, oye *Bishop* ti awọn *Anglican* ni pe enia ni lati jẹ oye Alufa kikun ko to le di *Bishop*, lẹhin na oye ti awọn *African Church* ki wọn to le di *Superintendent* tabi *Bishop* wọn ni lati jẹ Alufa kikun (*Full Priest*) nitorina ewo lo to ija ninu eyi?

Awọn ijọ ti wọn ko le sọ wipe *Superintendent* ti wọn dabi *Bishop* ni awọn ijọ *Brotherhood* nipa wipe ilana isin ti wọn ko lọ nipa a njoye *Deacon*, *Full Priest* tabi oye miran.

Gẹgẹ bi isin *Anglican* ti lọ ni nwọn nfi njẹ oye sin wọn; mo nran nigbati nwọn yan Ẹni-owọ *Archdeacon* T. A. J. Ogunbiyi fun oye *Archdeacon*, mo ro wipe ki iṣe oye ti nwọn da aṣọ rẹ lọtọ, *letter* (Iwe) *Bishop* ti Eko lo fi yan wipe a fi o jẹ oye *Archdeacon*; timọ ni oye na mọ o lori, ko si si ẹniti o sọ wipe o di igbati Ẹni-ọwọ yi ba de ilu oyinbo niwaju *Archbishop* ko to le di *Archdeacon*! njẹ ka bere lọwọ Oniwe-irohin yi tani nfi *Archbishop of Canterbury* jẹ?

*Bishop Tugwell* ti Ijọ *Anglican* ti wa ni ilu wa nibi fun iwọn ọdun diẹ ko to di wipe wọn fi oye D.D. ta a lọrẹ, Ekeji ẹwẹ, *Bishop Lang* ti Ijọ Aguda ilẹ yi ni nwọn fi jẹ oye *Bishop*. Ẹketa ẹwẹ, Ẹni-ọwọ *Arial* D.D. ti Ijọ Aguda ki iṣe *Bishop* bẹni o gba D.D. tabi ko ha tọ fun lati lo, nitoripe ki iṣe *Durham* lo fi ta lọrẹ, nitoripe Ẹni Ọwọ yi Ọgbọn Ori rẹ lo fi gba tabi ka sọ wipe odi igba ti o ba de iwaju *Arch bishop of Canterbury*. Eyi ko wa to fun Oniwe-irohin Eleti Ofẹ ko ye ku lori Oye ti ko kan lọwọ lẹsẹ.

Nitori na mo gba Oniwe irohin yi ni imọran ko ye jiyan lori ọrọ *Bishop* ko ṣe *Bishop* nitoripe iwe irohin Osẹ kẹta ti *African Messenger* ope Ẹni ọwọ J. S. Williams ni *Presbyter Bishop* ko wa jẹ bẹ nitotọ, nitoripe Ẹni owo yi ni ẹwu *Bishop* bo ba de ṣe idanwo lati gba D.D. yo gba, yio si ma lo Oye D.D. rẹ ti pẹkẹ ko ni mi, ko si si ẹni ti o ma ẹ lọwọ rẹ wo.

Mo dupẹ lọwọ rẹ Oniwe irohin Eko-Akete fun aye to fi silẹ fun mi lati sọ gbolohun diẹ fun Ọgbẹni Eleti-Ọfẹ.

Mo pari iwe mi,
KỌLAWỌLE.

---

## IGBẸ L' OWO WÀ.

EKURO.

Bi awọn oyinbo ile-òwò wọnyi ti gba Ọja (*Produce*) l' ọsẹ yi ni eyi.

Ẹgbẹ Odo-Ọya (Niger Co.)
G. B. Ollivant,
Oyinbo Agbẹra (Lagos Stores)
MacIver, African Association, John Holt, Miller Bros.

£13 10 fun *ton* kan

EPO.

£24 10 ni gbogbo awọn Ẹgbẹ oyinbo ti a darukọ wọnyi gba *ton* kan.

COCOA.

Lati £27, de £28, fun *ton* kan bakanna

---


## Sorinolu's Grammar School.

*The first ever Established in Abeokuta and Ijẹbu-Ode since 17 years ago.)*

All Grammar School Lesson efficiently taught to Advantage and Success.

*Tuition Fess Rated by the Readers:—*

Primers I and II—3/- *per Quarter*.
Readers I to III—3/- *per Quarter*.
Readers IV and V—6/- *per Quarter*.
Classes I to III—9/- *per Quater*.
Boarding Fee—£1 2s 6d, Monthly.

This is beside the Tuition Fee; and includes Lodging, Cloth-Washing, and Cooking Services.

PLEASE NOTE!

Payments strictly in advance; otherwise the Pupil shall suffer a temporary cessation from School and Boarding.

For futher particulars apply to

ARIYỌ ṢORINOLU,
*Principal & Proprietor.*

Iporo Ake, Abẹokuta.


E.
an? Goo... wọn y...
u nhu bayi ẹiwaju gbigbe-wọn niyawo

Apply to the Editor of this Paper.

## All for Bicycles and Motors.

Ask for KADUNA STORE,
No. 81, Ọdunfa Street,
Near the Famous Building of
Mr. Andrew Thomas, Lagos.

*At reduced prices*

Special Dunlop Bicycles Tyres Beaded-edge 12/-
do. do. 15/-

The above Tyres are specially for Rudge-withworth and German Cycles and we have complete workshop for repairing of all kinds of machinery. Send all your repairs' Bicycles, Motors, Sewing machines, Gramophone, painting, enamelling work soldering, etc., to the Properitor at the undermentioned address. All Bicycles spare parts on sale.

SAM. A. CLAY,
No. 1 Macauley Street,
or at Workshop, 81, Ọdunfa St.
Lagos.

*Telegram Address*:—KADUNA STORE,
81, Ọdunfa Street,
Lagos.

---

## IYA AFIN SABINA BỌLAJOKO

Ti No. 39, Ita Matinin jẹ ẹniti o gbaṣẹ ati ma ta orişirişi ỌTI o si nta awọn nkan Ipanu ni Şabu rẹ yi.

E lọ ke si i, Wara-ṣeṣa ni ọja rẹ, owo wọn si mọ-ni-wọn ti makunnu.

## *The Philharmonic Band.*



Awọn oni fere yi nfun pẹtẹ, ilù nwọn si dun bi oyin l' eti.

Owo ti a nfi pe nwọn ko pọ, nwọn ko si kọ lati lọ si ilu ki ilu.

Ẹni ba fẹ nwọn, ko kọ iwe si,
*THE SECRETARY.*
c/o Aafani Motors
The Marina Lagos.

---

"KỌ-OGE-NIWẸ" SEWING INSTITUTE,
119, TOKUNBỌ STREET, LAGOS.

MRS. FRANCES ADEYEMI THORPE (NEE GREEN) K'ogeniwẹ, a fi iṣẹ ni lapa ṣe fuja, bẹrẹ si Iṣẹ Ọna rẹ ni No. 119 Tokunbọ Street. Ni ti aṣọ riran ni aṣa orişirişi ko ni ẹgbẹ.

Ẹyin ọmọge ti nfẹ iṣẹ kọ, Ẹ lọ ri i.

## DRESS-MAKING.

"KỌ-OGE-NIWẸ" SEWING INSTITUTE,
119, TOKUNBỌ STREET, LAGOS.

If you want a perfect fit and artistically made dress, patronize the above institute and you will be amply satisfied.

Girls requiring tuition in the modern and up to date style of Dress-making please apply to the above Institute.

*TERMS MODERATE.*

---

## "O ŞE' WỌ NI!" (FAIR WARNING)

Ọgbẹni A. W. Olukolu Onigbanjo to gba Aṣẹ lọdọ Ijọba *Nigeria*, nta orişirişi ọja ni Gbanjo, nile Gbanjo rẹ ni 2, Isalẹgangan Street, l'Eko.

O si nta ile ati ilẹ pẹlu.

Awọn ọjọ ọja-tita ni iwọnyi. Monday, ati Thursday, lagogo mẹta ọsan. Saturday, lagogo mẹsan arọ, lọsọsẹ. O ntete san owo ọja fun enia. Ma ọja rẹ lọ si bẹ

irohin Eko-Akete fun gbo'ohun die fun MA.

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

**ROMAN CATHOLIC (HOLY CROSS)**

Masses will be sung by Priests appointed.
Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi. (MORNING)

Masses Isin Arọ.

6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.

(EVENING.)

Masses (Benediction) Isin Ibukun.

4.45—5.30 6.45—7.30.

ST. MICHAEL'S (Lafiaji.)

MORNING. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9.30 a.m.
EVENNING. 5.45—6.30 p.m.

**ANGLICAN**

| Time. | | Preacher. |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Christ Church | The Vicar |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | —St. Paul's (Breadfruit) | Rev. D. A. Fawẹhinmi |
| 6.30 p.m. | | Rev. W. Ayedun |
| 9 a.m. | St. John's (Aroloya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 6.30 p.m. | do | do |
| 9 a.m. & 4 p.m. | -St. Peter's (Aiapako) | Rev. J. A. Cole |
| 9 a.m. & 6.30 p.m. | Holy Trinity (Ebute Ero.) | Rev. S. J. Gansallo |
| 9 a.m.... | St. David's (Jordan) | Rev J. A. Leigh |

**WESLEYAN**

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | Tinubu | Rev. H. W. Stacey |
| 7 p.m. | do. | Rev. D. A. Bababunmi |
| 10.30 a.m. | Ereko | do. |
| 7 p.m. | do. | Rev. E. K. Ajai-Ajagbe |
| 10.30 a.m. | Olowogbowo | Rev. E. E. Williams |
| 7 p.m. | | Rev. J. A. Angus |
| 10.30 a.m. | Ọbun Eko | Bro. Adebiyi Tepowa |
| 7 p.m. | | Rev. S. A. Pearce |

**AFRICAN (COMMUNION)**

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Jehovah Shalom | Rev. J. F. Ogunko |
| 7 p.m. | do. | Bro. J. T. A. White |
| 9 a.m. | Erelu | Bro. J. A. Lalaleyẹ |
| 7 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | Bethel | Rev. Supt. G. A. Oke |
| 6.30 p.m. | | Rev. J. W. Bara |
| 9 a.m. | Zion | Bro. E. M. Olulode |
| 6.30 p.m. | do. | Bro. B. A. Robter |
| 10.30 a.m. | African Methodist | Bro. A. T. Iroko |
| 4.30 p.m. | | Bro. J. A. Oshodi |

**FIRST BAPTIST CHURCH**

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | | Bro. J. O. John |
| 6.30 p.m. | | Rev. J. R. Williams |
| 9 a.m. | Arárọmi (Baptist) | Bro. Joseph Adewuyi |
| 4 p.m. | | Bro John Apena |

**EBENEZER (BAPTIST)**

Bro. J. J. Tubi
Bro. Joseph Adekoya

**BROTHERHOOD**

7.30 a.m. Ilupesi — Bro. E. A. Adegun
7 p.m. — Pastor A. Adedeji Isọla

**St. STEPHEN'S (EPETEDO)**

9 a.m. & 4 p.m. — Bro. Thomas Akajagbo

**AHMADIA (ISLAM)**

6 a.m. Fajir Service Y. P. O. Ṣodẹyinde
5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. Ajoṣe (Bamgboṣe Street.)

**COLONIAL CHURCH (ODAN)**

8 a.m.—Holy Communion

6.45 p.m.—Evensong and Sermon ; Ven. Archdeacon A. W. Smith

**SALVATION ARMY.**

Services at Glover Memorial Hall, 10 a.m. and in the Streets.

---


W' O BI, ẸNIKEJI, OJU L'ỌRỌ WÀ!!

Maṣini Aranṣọ ti a npe ni "MUNDLOS" wa fun tita niti Ọgbẹni J. S. JOHNSON ti 16, Ita ọja Ajaṣẹ, ati ni Ṣabu ALAJ MASU ni Ita Agarawu ni owo ọpọku-ọyọku.

Ni Ile-iwo oriṣiriṣi ọja ti Ọgbẹni ARNOLD SCHLESINGER, Oniṣowo ara Jamani ni Ita 7, Labinjo, leti Ita William

lẹ gbe le ri awọn ẹrọ RECORDS ohun orin ijọ to ṣẹṣẹ de ra ati awọn Ẹrọ wọnyi.

Ẹrọ ohun-orin GRAMOPHONE

Kẹkẹ-olo-gere BICYCLE

Awo Abọmafọ ENAMELWARES

Waji BLUE ati ogunlọgọ ọja miran.

Ẹ sure tete lọ ra ti nyin nibẹ.

MESSRS. J. R. THOMAS & SONS of Lisabi Hotel, Ilori, beg to inform the public in general that they have been licensed by the Nigerian Railway to sell and serve refreshments etc etc. to all passengers travelling on trains on up and down journey at Ilori and Olokemeji Stations at very moderate prices. This venture has already been opened by them to the public at the aforesaid Stations any one travelling up to Ibadan and back, and needing supply of any kind of refreshment should intimate us through the Station Masters Iddo to Ibandan, and *vice versa*.

---

"EKO AKETE."

A le ri Iwe-Irohin yi ra lọdọ Aṣoju wa.

Ajenifuja Stores, 109 Broad Street, LAGOS.

Ọgbẹni VIDAL R. COLE.

---

WHY LOOKING SAD.?

Are you impotent, suffering from sexual weakness, nervous postration or loss of memory why don't you use Muiracithin and get instant relief. It will rejuvenate you, and restore your youthful energy. Its effect is wonderful and permanent. No matter how Chronic your case may be. It is also unsurpassed remedy for women in case of barreness, irregular Menstruation sexual Neurasthenia etc., etc. In order that every sufferer should have a trial of this valuable Medicine, the prices are reduced for only limited time at 4/6 in bottle of 50 pills, and 6/6 in bottle of 100 pills obtainable at "Ajenifuja" Store No. 109 & 111, Broad Street.

VIDAL R. COLE.
*Sole Agent.*

---

FIRST CLASS TONSORIAL ARTIST

Mr. A. L. KOSỌKỌ the well-known Barber late of Customs Street, Lagos, begs leave to inform his many clients of his new Establishment at 135, Victoria Road, this City, where prompt attendance will be accorded them as heretofore.

Razors, Combs, Perfumes, etc, are also on sale at prices to suit everybody.

Call or send; warm wellcome to all.

NOTICE.

When replying advertisers, please mention "Eko Akete"

---

AKIYESI.

Ti ẹ ba fẹ lọ si ọdọ awọn ti o polowo ọja sinu Iwe-irohin yi, ẹ jare ẹ sọ pe ninu iwe-irohin Eko Akete ni ẹ ti ri ipolowo ọja na ka.

---

First Class Dressmaking!!!

Mrs. ABRAHAM ASHARR trained in Paris, begs to offer her professional services to the public.

Latest modes at moderate charges satisfaction gauranteed. Call at once at

117, Victoria Road,
Lagos, Nigeria.

---

PAGIDARI!

*Olokiki* S. FRANCIS LAWANI *Saka-jojo.*

Onișowo ni Victoria Road ni wabiẓwọsi ohun elo, fun Ọmọge ati Ọmọde-in'ẹṣọ ti o si nta ni ita oloko-o-gbowo.

O si tun ni ayẹ pataki kan ninu ile ọja na, ti a nṣe Gbajamọ fun ni, ni owo-ti-kotani-lara, bi ṣile kan, sisi, tabi tọrọ.

Egbogi oriși-rișì iwosan onirunru aisan, Ipara olo-ọrun. ati agbọrun Jigin-oju, ati nkan mere-mere pọ to wọbu nibẹ.

Ikan-o-jọkan irin iṣẹ ati Egbogi ti a fi nya *Photo* aworan wa nibẹ ni ọpọku yọku.

Oniru-nru wosiwosi ti a ko le ka tan pọ nibẹ bere ohun-ko-hun ti o ba nfẹ yio pese rẹ fun ọ.

O ngbero laipẹ, lati și ile Erọ Idan Awoșẹju ti a npe ni *(Cinema)* ni Great Bridge Street, Iduumagbo.

Ṣoroko a gbe ṣeranwo ni igbati o ba și ibẹ
Irohin ko to afojuba.

*P.O.Box 159* *Phone 214*

## ALASE LEATHER FACTORY.

### "ILE ALAWỌ."

Sole-Leather tanned in a most modern style and Upper-Leather prepared in all colours, namely:—Black, White, Red, Yellow and Green, are obtainable at very cheap prices.




Awọ Bata ni ọpọku ọyọku. Kọwe ṣowọ yala ni ede Yoruba tabi ti Gẹsi pẹlu owo si:—

E. B. BEYIOKU-ALASẸ
108, Moloney Bridge St.
P. O. Box 368, Lagos, Nigeria.
*Telegrams* —Alawọbata, Eko.

## ỌBẸ L' ỌMU AGBA

A nlẹ "Kúkù" to mọ orisirisi Onjẹ Ilẹ wa ni sise. To si le jẹ ki ọbẹ ma sọ "Tapa" lori ina. To si mọ "Kọtọ" Ọbe di lọwọkan.

A o sanwo Ọṣu to rọju fun ẹniti o ba mọ iṣẹ yi se.

E kọwe si Oniwe Irohin yi.

## AWỌN IWE ỌGBẸNI J. G. KUYẸ

Fun Ile Eko.

| | | |
|---|---|---|
| A. B. D. Alaworan | ... | 3d. |
| Iwe Alaworan Kini | ... | 7d. |
| Iwe Alaworan Keji | ... | 9d. |

Awọn iwe wọnyi ko ti si lode ni sa kan nitori ogun Germani, ṣugbọn wọn tun de nisisiyi, a si le ri wọn ra ni Ile Iwe tita ti C.M.S. ninu ilu yi tabi lẹhin odi.

Itan ati owe ti o wa ninu iwe wọnyi dara pupọ, bẹ gẹgẹ ni awoko ti wọn dara fun ọmọde to, ẹniti o ba dan a wo yio si pe ẹgbọn ẹniti o ti jẹ olukọ awọn ọmọde fun ọdun pupọ li a ti to awọn iwe na lẹsẹsẹ, kiṣe iṣe *sare nbaja.*

A le ri awọn iwe wọnyi ra pẹlu lọdọ oniwe ni ẹdin owo, 66, Ibadan Street, Ebute Mẹta.

## GIDIGBO! GIDIGBO!! HEYA!!!



Awọn RECORDS to nkọrin lede YORUBA pọ to-wọbu ni ile owo.

MANN POOLE & COMPANY LTD
8, TINUBU SQUARE, LAGOS.

Ki la ti nṣ' oku l' ọrun?
Ki la ti nṣ' ori nile Iku?
Tutu tabi Gbigbẹ?

Ọpọkuyọku si ni, wa ṣa eyi to wu ọ ni:—
8, TINUBU SQUARE, LAGOS.

Printed at "Tika-Tore" Printing Works, 20, Market Street, Lagos, and Published by Adeoye Deniga at 24, Williams Street, Lagos, Writer and Lecturer.